# "AYÉ Ń YÍ" LỌ̀RỌ̀ AṢỌ WÍWỌ̀ DÀ LÁWÙJỌ YORÙBÁ

**Tìámíyù Rasaq Ọdẹyẹmí ati Ọlátáyọ Basirat Adéfúnkẹ**
Department of Yorùbá, School of Secondary Education, (Languages)
Oyo State College of Education, Lanlate.
tiamiyurasaq66@gmail.com +234(0)7066485905 & olatayobasirat406@gmail.com +234(0)7065742252

***Àsamọ̀***

*Lóde-òní, àṣà alásà kò jẹ́ kí á mọ ohun iyì àti ẹ̀yẹ tí ó wà nínú kí á wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá mọ. Àwọn ọmọ bíbí Yorùbá tí ń kó iyán àṣà aṣọ ìbílẹ̀ wa ní wíwọ̀ kéré nítorí ọ̀làjú. Nínú àwọn ẹ̀yà tí wọ́n mọ rírì aṣọ wíwọ̀ ni ìran Yorùbá wà ní gbogbo àgbáyé. Ohun tí iṣẹ́ yìí ṣe ìwádìí lé lórí ni ojú tí àwọn ọmọbíbí ìran Yorùbá fi wo wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ lóde-òní. Ṣé Yorùbá bọ̀ wọ́n ní "ilé la ti ń kẹ́ṣọ̀ọ́ ròde". Iṣẹ́ yìí ṣàwárí àwọn ìpèníjà tó ń kojú àṣà ìwọṣọ ìràn Yorùbá bí i ọ̀làjú, òbí, ẹ̀kọ́ ìgbàlódé, ìtẹ̀mẹ́rẹ̀ àṣà tí ó ṣe okùnfà àìnífẹ̀ẹ́ èdè àti àṣà Yorùbá mọ́, ẹ̀sìn ìgbàlódé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Iṣẹ́ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé bí àwọn òbí àti alágbàtọ́ bá lè fi ọwọ́ ọ̀tún mú fífi àṣà wíwọ aṣọ ilẹ̀ Yorùbá kọ́ àwọn ọmọ láti kékeré, aṣọ ìwùkọ́wọ̀ yóò dínkù jọjọ láwùjọ Yorùbá. Púpọ̀ nínú àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ mánigbàgbé lórí onírúurú aṣọ ìran Yorùbá láyé àtijọ. Àfikún ti iṣẹ́ yìí ṣe ni wíwo ìhà tí àwọn ènìyàn kọ sí wíwọ̀ aṣọ Yorùbá ìbílẹ̀ Yorùbá lóde-òní. Ìrètí wa ni pé iṣẹ́ yìí yóò ṣiṣẹ́ alóre fún gbígbé àṣà wíwọ aṣọ ìran Yorùbá láruge ju bí ó ṣe wà lọ.*

**Kókó ọ̀rọ̀:** Àwùjọ Yorùbá, Àṣà Yorùbá, Aṣọ wíwọ̀, Àwùjọ òde òní àti ìgbéláruge àṣà

## Ìfáárà

Ohun kan pàtàkì ni aṣọ wíwọ̀ jẹ́ nì àwùjọ Yorùbá. Àròfọ̀ ìsàlẹ̀ yìí ṣàtẹnumọ́ bí aṣọ ṣe ṣe pàtàkì tó láàrin ẹ̀yà Yorùbá.

*Aṣọ ṣẹ pàtàkì, aṣọ ṣe kókó*
*Aṣọ la fi ń bàsírí ara*
*Bí ó bá sí ẹ̀wù*
*Onírúurú ara là bá rí . . .*
*Bí ó bá sí sòkòtò*
*Onírúurú ìdí là bá rí*
*Bí i kókó, bí i oówo, bí i ìkù, bí i àgbáàrín*
*Aṣọ! Aṣọ la fi ń bàsírí ara (William, 2018, ay)*

Ìmúra nípa aṣọ wa máa ń sọ̀rọ̀ bì ò tilẹ̀ jẹ́ pé kò ní ẹnu bí ohun abẹ̀mí bí ènìyàn, ẹranko, ẹyẹ tàbí ohun afàyàfà. Ohun púpọ̀ ni àkòrí yìí kò sínú eyi tí ó kọjá aṣọ wíwọ̀ ni ìlẹ̀ Yorùbá. Lára ohun tí ìmúra kò sínú ni irun síṣe, ẹyín pípa, ilà kíkọ, ìlẹ̀kẹ̀ lílò, yẹrí etí, làálì lílé, osùn kúkùn tàbí tìróò lílé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Aṣọ́ jẹ́ ohun tí ènìyàn ń wọ̀ láti bo ìhòhò ara. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan aṣọ ni ìran Yorùbá ní, èyí ni ó sì yà wọ́n sọ́tọ̀ láàrin àwọn ẹ̀yà tó kù. Lára ẹ̀yà tó gbọ́ ẹ̀ṣọ́ ní ìran Yorùbá wà pẹ̀lú bí wọ́n ṣẹ máa n ṣe àfihàn rẹ̀ nibí gbogbo ayẹyẹ ọlọ́kan-ò-jọ̀kan bí ìsìnkú, ìsọmọlórúkọ, ìgbéyàwó, ìṣílé, oyè jíjẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìran Yorùbá mu ìmúra níbàádà débi pé, wọ̀n nígbàgbọ́ pé ìmúra máa ǹ sọ irú ẹni tí ènìyàn jẹ́ àti irú ìdílé tàbí ilé tí ẹni náà tí jáde wá, ìpò tàbí ayé tí irú ẹni bẹ́ẹ̀ wà nínú àwùjọ. Onírúurú aṣọ ní àwọn Yorùbá máa ń wọ̀. Aṣọ iṣẹ́ wà tì ó jẹ́ èyí tí wọ́n máa ń wọ̀ lọ síbi iṣẹ́. Àwọn iṣẹ́ àbáláyé, tí ìran Yorùbá máa ń dá aṣọ fún ni iṣẹ́ ọdẹ, iṣẹ́ àgbẹ̀, isẹ́ ẹkù fífọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gbérí ọdẹ ni aṣọ àwọn ọdẹ, ti gbérí àgbẹ̀ sì jẹ́ ti aṣọ àwọn àgbẹ̀. Gbérí ọdẹ máa ń tobi ju gbérí ti àwọn àgbẹ̀ lọ torí pé ó máa ń ni àpò ńlá ní ojú àti lẹ́yìn. Aṣọ ìṣeré tàbí ìyílè náà wà tí àwọn Yorùbá máa ń wọ̀ tí wọ́n bá fẹ́ ṣeré, àwọn bii bùbá àti ṣòkòtò, sọ́ọ̀rọ́ àti dàmáàsi. Bákan náà ni wọ́n ní aṣọ ìmúròde tí ó wà lóríṣiríṣi tí wọ́n máa ń wọ̀ lọ síbi onírúurú ayẹyẹ. Àwọn aṣọ tó wà fún ìmúròde ni bùbá àti ṣòkòtò, bùbá agbádá àti ṣòkòtò, dàńsíkí, dàńdóógó, gbárìyẹ̀, Ṣapará àti ọ̀yàlà. Aṣọ ìfinijoyè yàtọ̀ sí aṣọ ayẹyẹ ìsìnkú, ìkómọjáde, ìṣílé, ìgbéyàwó. Ẹni tí ìran Yorùbá bá fẹ́ fi oyè dálọ́lá, ìmúra irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ ni yóó ṣàfihàn rẹ̀ pẹ̀lú wíwọ aṣọ tí ó gbayì, lílò bàtà tí ó jọjú nígbèse, ìlẹ̀kẹ̀ lílò sọ́wọ́ pẹ̀lú ìrùkẹ̀rẹ̀ funfun lọ́wọ́, pàápàá tí ó bá jẹ́ oyè Ọba. Onírúurú aṣọ aláràbarà ni àwọn Yorùbá máa ń wọ̀ níbi oríṣiríṣi ayẹyẹ. Awọn ọ̀tọ̀kùlú ènìyàn ni wọ́n sábàá máa ń wọ irú àwọn aṣọ tó

wuyì bẹ́ẹ̀. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé, "ìrínisí ni ìṣe ni lọ́jọ̀", "bí a ti rìn ni àá koní". Bí awọn ọkùnrin ní aṣọ tiwọn, bẹ́ẹ̀ ni àwọn obìnrin náà ní pẹ̀lú. Nítorí pé ẹ̀yà Yorùbá jẹ́ ẹ̀yà tó fẹ́ràn òde àríyá púpọ̀ ni wọ́n ṣe ya onírúurú aṣọ ńlá
sọ́tọ̀ fún òde àríyá.

Ní ayé àtijọ́, aṣọ tí a mọ àwọn ọkùnrin mọ̀ ni bùbá, sapará agbádá, dáńsíkí, ṣòkòtò sọ́ọ̀rọ́, ṣòkòtò kẹ̀ǹbẹ̀, ọ̀yàlà, gbárìyẹ̀, dà ni ìró, bùbá, ìpèlé, ìborùn, tòbí, àgbékọ́, yẹ̀rì àti gèlè. Ní àwùjọ Yorùbá, ìmúra ni ìlànà ni oríṣiríṣi, ìmúra kò tí ì pé láìlo fìlà tò bá a mu./ Ohun àkọ́kọ́ pàtàkì tí a ní láti mọ̀ nígbà tí a ba lo fìlà ìbílẹ̀ ni pé, ó gbọ́dọ̀ bá aṣọ tí a wọ̀ sọ́rùn mu. Èyí n ṣàfihàn ọ̀kan lára ìpèdè Yorùbá tó sọ pé "bí a ó ri tàǹgíìri, awọ ò hu" ni ọ̀rọ̀ fìlà rí sí onírúuru aṣọ ìbílẹ̀ tí ó wù kí á wọ̀ sọ́rùn". Fìlà jẹ́ ohun èlò tí ó ṣe lọ́mú-lọ́mú, tí ó lẹ̀ lọ́wọ́ tí ọ̀pọ̀ ọmọ Yorùbá ti wọ́n wà ní apá Ìwọ̀ oòrùn Áfíríkà pàápàá náà ń lò ó. Fìlà lè jẹ́ àfọwọ́ṣe tàbí onírírán látara ohun èlò aṣọ bíi aṣọ òkè, dàmáàsìkì, àdìrẹ, òwú, ẹtù àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀. Oríṣiríṣi fìlà ni àwọn ẹ̀yà Yorùbá máa ń lò sì onírúurú aṣọ ìbílẹ̀ tí wọ́n ń lò láti ìgbàdégbà. Àwọn oríṣiríṣi fìlà bíi fìlà gọ̀bì, fìlà abetí-ajá, fìlà onídẹ, fìlà àdìro, fìlà kufi, fìlà ìkorí àti fìlà Awólọ́wọ̀ ni ó ń ṣe ẹwà fún wíwọ aṣọ ìbílẹ̀. Ìmúra ní ìlànà ìbílẹ̀ kò tí ì pé bí a kò bá lo fìlà pẹ̀lú rẹ̀. Yorùbá máa ń wo àwọ̀ kan lára aṣọ kí wọ́n tó yan fìlà ti wọn yóò lò pẹ̀lú rẹ̀, àyàfi tí aṣọ bá jẹ́ aláwọ̀ kan bí aṣọ aláwọ̀ funfun, aláwọ̀ dúdú tàbí aláwọ̀ amọ̀. Ìmúra ọkùnrin kò tí ì pé tí kò bá sí fìlà níbẹ̀. Ìran Yorùbá máa ń dé fìlà gẹ́gẹ́ bí ẹ̀ṣọ́ orí láti fi kún ìmúra tiwa-n-tiwa nígbà tí a bá wọ oríṣiríṣi aṣọ.

**Ìdojúkọ tí ó ti dé bá aṣọ wíwọ̀**

Ipò tí àṣà ìmúra nípàtàkì aṣọ wíwọ̀ láàrin ẹ̀yà Yorùbá wà báyìí kò ṣe é fẹnu ṣọ rárá. Láti fi ipò àṣà ìwọṣọ hàn, oríṣiríṣi kùdíẹ̀-kùdíẹ̀ ni ó wà níbẹ̀, ọ̀làjú kò jẹ́ kí aṣọ wíwọ̀ ní ìlànà ìbílẹ̀ fẹsẹ̀ múlẹ̀, ọ̀pọ̀ àwọn ọ̀dọ́ àti ògowẹ̀ẹrẹ ni kò lé wọ aṣọ ìbílẹ Yorùbá tó ṣàfihàn ìwà ọmọlúàbí àfi ìmúra àmúlùmálà. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó nira fún àwọn ọmọbíbí Yorùbá láti wọ aṣọ ìbílẹ̀ wọn. Iṣẹ́ ìwádìí yìí yóò ṣe àyẹ̀wò sí àwọn nǹkan tó ń ṣe okùnfa kíkọ́ nípa àṣà ìmúra àti mímọ̀ nípa àǹfààní tó wà nínú wíwọ aṣọ tó ń ṣe àfihàn jíjẹ́ ọmọlúàbí ní àwùjọ pẹ̀lú ọgbọ́n àti wá ìyànjú tàbí ọ̀nà àbàyọ sí àwọn ìṣòrò tó dàbí èṣù lẹ́yìn ìbejì fún wíwọ asọ ní ìlànà ìran Yorùbá.

**Èrò àwọn Onímọ̀ nípa Ìmúra**

Olúwajọba àti Ọláwoyè (2016) ní nínú gbogbo àwọn ìran tó wà nínú ayé, àwọn ìran Yorùbá kò kéré nínú asọ wúwọ̀. Àwọn ẹ̀yà Yorùbá ti ń wọ asọ ojọ́ ti pé. Àwọn Yorùbá ní onírúurú asọ ìbílẹ̀ tí à ń lò láti ìgbàdágbà
William, Amos àti Nurudeen (2018) ṣàfihàn bí asọ wíwọ̀ ṣe ṣe pàtàkì tó ní ilẹ̀ Yorùbá. Èyí ni ó fa sábàbí tí àwọn Yorùbá fi ní orísirísi asọ fún onírúurú iṣẹ́ àti àkókó. Tiamiyu (2004) ṣàtẹnumọ́ pé kí àṣà òyìnbó tó gbòde, asọ àwọn Yorùbá yàtọ̀ sí àmúlùmálà bí i tòde òní. Bí ọkùnrin ṣe ní aṣọ tiwọn ni àwọn obìnrin náà ní tiwọn bákan náà. ó m ẹ́nuba orísirísi asọ bíi asọ isẹ́, asọ ìwọ́lẹ̀ àti asọ ìmúròde. Adérìnóyè, Adeleke àti Adélóre (2019) náà sọ pé, ó má a ń fi ìyàtọ̀ hàn láàrin ọkùnrin àti obìnrin.

**Ọgbọ́n Ìwádìí**

Kí iṣẹ́ ìwádìí ba à lè tẹ̀wọ̀n kí ó sì jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà, olùwádìí nílò ọgbọ́n tí kò ni àléébù rárá. A pèsè àkójọ ìbéèrè fún àwọn àgbàlagbà àti àwọn ògo-wẹ̀ẹrẹ tí ọ̀rọ̀ kàn nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí. A fi gbèdéke sí ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè tò wà nínú àkójọ ìbéèrè ìwádìí wọ̀nyí bóyá "bẹ́ẹ̀ ni" tàbí "bẹ́ẹ̀ kọ́". Àkójọ ìbéèrè yìí ní a mú lọ fún àwọn onímọ̀ tó ní ìmọ̀ nípa rẹ̀ láti ṣe àtúnṣe níbi tí ó bá yẹ, kí ó ba à le tẹ̀wọ̀n.Àwọn àgbàlagbà tí a lò jẹ́ ọgọ́ta (60) tí àwọn ọ̀dọ́ sì jẹ́ ọgọ́fà (120). Ìpín wẹ́wẹ́ wọn lọ báyìí; àgbàlagbà ọgbọ̀n ní ìlú Èrúwà àti ọgbọ̀n ní ìlú Làǹlátẹ̀ ni Ìjọba Ìbílẹ̀ Ìwọ̀-oòrùn Ìbàràpá ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́. Bákan náà ni a pín àwọn ògowẹ̀ẹrẹ wọ̀nyí sí ọgọ́ta ní ìlú kọ̀ọ̀kan, ìyẹn ọgọ́ta ènìyàn láti Èrúwà, tí ọgọ́ta náà wá láti ìlú Làǹlátẹ̀.

**Àwùjọ Àfojúsùn**

Gbogbo àwọn tí ó jẹ́ ìran Yorùbá tí ó wá ní ìjọba ìbílẹ̀ Iwọ̀-oòrùn Ìbàràpá ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ ní ó lẹ́tọ̀ọ́ láti kópa nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí.

**Atọ́nà ìbéèrè Ìwádìí:**

1. Ìhà wo ni àwọn ọ̀dọ́ kọ sí aṣọ wíwọ̀?
2. Kí ní ìhá àti ìwúrí tí àwọn òbí ń fun àwọn ọmọ tó fẹ́ràn wíwọ aṣọ ìbílẹ̀
3. Ṣe àǹfààní wá nínú wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ láwùjọ Yorùbá?
4. Ǹjẹ́ àwọn òbí nífẹ̀ẹ́ sí kí àwọn ọmọ wọn máa wọ aṣọ ìbílẹ̀?
5. Àwọn ìpèníjà wo ló ń kojú àwọn ènìyàn tó fẹ́ràn wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ láwùjọ?

**Títẹ́pẹpẹ Àkójọpọ̀ Èròjà Àmúkalẹ̀ Fáyẹ̀wò**

Ọ̀nà ìṣirò ìgbéléwọ̀n orí ìdá ọgọ́rùn-rún ni a lò nínú iṣẹ́ ìwádìí fún pépà yìí. Ohun tí ó mú wa lo ọ̀nà ìṣirò yìí ni pé kò rújú, bẹ́ẹ̀ ní ó rọrùn. Òtẹ méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a lò fún iṣẹ́ ìwádìí yíì, tábìlì àtẹ àkọ́kọ́ ṣe àfihàn ìhà tí àwọn ọ̀dọ́kùnrin àti ọ̀dọ́bìnrin kọ sí aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá, tábìlì àtẹ kejì ni ti àwọn àgbàlagbà lọ́kùnrin àti lóbìnrin.

**Ìhá tí àwọn ọ̀dọ́kùnrin àti ọ̀dọ́bìnrin kọ sí Ìbéèrè Ìwádìí**

| S/N | ÌBÉÈRÈ | BẸ́Ẹ̀ NI | ÌDÁ ỌGỌ́RÙN-ÚN | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ | ÌDÁ ỌGỌ́RÙN-ÚN |
|---|---|---|---|---|---|
| 1. | Mo fẹ́ràn wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá | 20 | 16.7% | 100 | 83.3% |
| 2. | Aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá máa ń nira ní wíwọ̀ | 60 | 50% | 60 | 50% |
| 3. | Aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá kì í jẹ́ kí ń rẹwà tí mo bá wọ̀ ọ́ | 90 | 75% | 30 | 25% |
| 4. | Ojú máa ń tì mí tí mo bá wọ̀ ọ | 80 | 66.7% | 40 | 33.3% |
| 5. | Aṣọ Yorùbá kì í ṣe aṣọ ìgbàlódé | 100 | 83.3 | 20 | 16.7 |
| 6. | Àwọn èniyàn máa ń fi mi ṣe yẹ̀yẹ́ ti mo bá wọ aṣọ Yorùbá | 38 | 31.7 | 82 | 68.3 |
| 7. | Aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá kò ṣe é wọ̀ lọ sí ibi iṣẹ́ ọbà | 92 | 76.6 | 28 | 23.4 |
| 8. | Aṣọ tí ó máa ń wùwo lára ni aṣọ Yorùbá | 85 | 70.8 | 35 | 29.2 |
| 9. | Àwọn tí kò lájú ni ó máa ń wọ aṣọ yìí | 108 | 90 | 12 | 10 |
| 10. | Aṣọ Yorùbá tẹ̀tè máa ń ṣàfihàn irú ẹ̀yà tí ẹ̀nìyàn jẹ́ | 115 | 95.8 | 05 | 4.2 |
| 11. | Mo fẹ́ràn láti máa wọ àwọn aṣọ tí ó n fí ara sílẹ̀ | 96 | 80 | 24 | 20 |
| 12. | Owo aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá máa ń gara láti rà | 40 | 33.3 | 80 | 66.7 |
| 13. | Wíwọ aṣọ tòkè tilẹ̀ Yorùbá ni kò jẹ́ kí n nífẹ̀ẹ́ síi | 88 | 73.3 | 32 | 26.7 |
| 14. | Aṣọ ìgbàlódé/òyìnbó rọrùn láti wọ̀ | 68 | 56.7 | 52 | 43.3 |
| 15. | Àwọn aṣọ fàyà sílẹ̀ ni mo fẹ́ràn láti máa wọ̀ | 68 | 56.7 | 52 | 43.3 |
| 16. | Àgbọ̀nrín ẹ̀ṣín ni ẹni tí ó bá ń wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá ń jẹ lọ́bẹ̀ | 82 | 68.3 | 38 | 31.7 |
| 17. | Torí pé àwọn òbí mi kì í wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá ni ó múmi kórira rẹ̀ | 84 | 70 | 36 | 30 |
| 18. | Ní Ilé ẹ̀kọ́ mi, olùkọ́ èdè Yorùbá | 30 | 25 | 90 | 75 |

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| | wa kì í wọ aṣọ ìbílẹ̀ wá sí ilé ìwé | | | | |
| 19. | Mi o kì í fetí sí àwọn ètò tò jẹ mọ́ àṣà àti ìse lórí rẹ́díò àti tẹlẹfísàn | 115 | 95.8 | 05 | 4.2 |
| 20. | Fílà dídé àti gèlè wíwé sí aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá ni ó mú aṣọ Yorùbá wù mí | 41 | 34.2 | 79 | 65.8 |

**Àlàyé lórí Ìhà tí àwọn ọ̀dọ́kùnrin àti ọ̀dọ́bìnrin kọ sí ìbéèrè ìwádìí**

Lórí ìbéèrè àkọ́kọ́, àwọn ọ̀dọ́ yálà ọkùnrin tàbí obìnrin fi èrò wọn hàn lórí wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá. Àwọn tó fẹ́ràn wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá jẹ́ ogún (16.7%), tí èèyàn ọgọ́rùn-ún (83.3%) ni àwọn kò fẹ́ràn wíwọ aṣọ ìbílẹ̀. Iye kan náà ni àwọn tó dáhùn ìbéèrè kejì gbà (50%). Àwọn tó ní aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá kìí gbé ẹwà wọn yọ tí wọ́n bá wọ̀ọ́ jẹ́ àádọ́sàn-án (75%), tí àwọn tí ó ní kò rí bẹ́ẹ̀ jẹ́ ọgbọ̀n (25%). Nínú ìbéèrè kẹrin àwọn tó sọ pé ojú máa ń ti àwọn tí àwọn bá wọ aṣọ ìbílẹ̀ jẹ ọgọ́rin (66.7%) nígbà tí àwọn ogoji (33.3%) èèyàn ni ojú kìí ti àwọn. Ìbéèrè kaàrún sàfihàn pé aṣọ Yorùbá kì í ṣe aṣọ ìgbàlódé ọgọ́rùn-ún ènìyàn (83.3%) ló ni bẹ́ẹ̀ ni, tí ogún ènìyàn (16.7%) sì ní "bẹ́ẹ̀ kọ". Nínú ìbéèrè kẹfa, ènìyàn méjìdínlógójì (31.7%) ló ní ojú máa ń ti àwọn tí àwọn bá wọ aṣọ Yorùbá tí ènìyàn méjìlélọ́gọ́rin (68.3%) ni kò rí bẹ́ẹ̀. Àwọn méjìléláàdọrin (76.6%) ló ní aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá kò ṣe é wọ̀ lọ sí ibi iṣẹ́ ọba, nígbà tí ènìyàn méjìdínlọ́gbọ̀n (23.4%) ni "bẹ́ẹ̀ kọ́". Àwọn ènìyàn márùnlélọ́gọ́rin (70.8%) sọ pé aṣọ tí ó máa ń wúwò lára ni aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá máa ń jẹ́ nígbà tí àwọn márùndínlógójì (29.2%) ní "bẹ́ẹ̀ kọ́". Lórí ìbéèrè kẹsàn-án, ìdá àádọrùn (90%) ni àwọn tí kò lajú ni ó ń wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá, tí ìdá mẹ́wàá (10%) sì ní ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀. Àwọn ènìyàn mẹ́rìdílọ́gọ́fà (95.8%) fèrò wọn hàn pé aṣọ Yorùbá tètè máa ń ṣàfihàn irú ẹ̀yà tí ènìyàn jẹ́, nígbà tí àwọn márùn-ún (4.2%) tako èrò yìí. Ìdá ọgọ́rin (80%) ni àwọn akópa tó nífẹ̀ẹ́ sí wíwọ aṣọ tí ó ń fara sílẹ̀, tí ìdá ogún (20%) ní "bẹ́ẹ̀ kọ́" Ìbéèrè kejìlá sàfihàn ènìyàn ogójì (33.3%) tí ó sọ pé owó aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá máa ń gara láti rà, nígbà tí ènìyàn ọgọ́rin (66.7%) ní "bẹ́ẹ̀ kọ́". Àwọn ènìyàn márùndínlọ́gọ́fà (73.3%) ló ní wíwọ aṣọ tòkè-tilẹ̀ Yorùbá ni kò jẹ kí àwọn nífẹ̀ẹ́ sí i, tí àwọn méjìlélọ́gbọ̀n (26.7%) nífẹ̀ẹ́ sí ì. Nínú àwọn akópa tó jẹ́ ọgọ́fà, àwọn méjìdínláàdọ́rin (56.7%) gbà pé aṣọ ìgbàlódé/òyìnbó rọrùn ní wíwọ̀ ju aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá lọ, tí méjìléláàdọ́ta (43.3%) ní kò rí bẹ́ẹ̀ nínú ìbéèrè kẹrìnlá

Ìbéèrè kẹ̀ẹ̀dógún ṣàfihàn àwọn akópa méjìdínláàdọ́rin (56.7%) tí wọ́n fẹ́ràn láti máa wọ aṣọ fàyà sílẹ̀, tí àwọn méjìléláàdọ́ta (43.3%) ni àwọn kò fẹ́ràn irúfẹ́ aṣọ bẹ́ẹ̀. Àwọn méjìlélọ́gọ́rùn (68.3%) ló ni àgbọ̀nrín ẹ̀sín ni àwọn tí ó ń wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá ń jẹ lọ́bẹ̀ sùgbọ́n àwọn akópa méjìdinlogoji (31.7%) ló ní ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀ nínú ìbéèrè kẹrìndínlógún.

Nínú ìbéèrè kẹtàdínlógún, àwọn akópa mẹ́rìnlélọ́gọ́rin (70%) ní, torí pé àwọn òbí àwọn kì í wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá ní ó mú kí àwọn kóríira rẹ̀, tí àwọn mẹ́rìndínlógójì (30%) ni ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀. Ìbéèrè kejìdínlógún se àfihàn ọgbọ̀n akópa (25%) tí wọ́n sọ pé torí pé olùkọ́ èdè Yorùbá ní ilé ẹ̀kọ́ àwọn kì í wọ aṣọ ìbílẹ̀ ni àwọn kò fi nífẹ̀ẹ́ sí i, tí àádọ́rùn-ún (75%) nínú àwọn akópa ní ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀. Ìbéèrè kọkàndínlógún, ní ìdá márùndínlọ́gọ́rùn ún (95%) nínú ọgọ́rùn-ún ló ní àwọn kì í fetí sí àwọn ètò tó jẹ mọ́ àṣà àti ìṣẹ Yorùbá lórí rédíò àti tẹlifíṣọ̀n, ìdá márùn-ún (5%) ní àwọn máá ń gbọ́ ètò tó jẹ mọ́ àṣà àti ìṣe Yorùbá. Nínú ìbeèrè ogún, àwọn akópa mọ́kànlélógójì (34.2%) ṣàlàyé pé dídé fìlà àti wíwé gèlè sí aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá ni ó mú aṣọ Yorùbá wu àwọn, tí akópa mọ́kàndínlógọ́rùn-ún (65%) ni fìlà dídé àti gèlè wíwé sí aṣọ Yorùbá ni kò jẹ́ kí àwọn fẹ́ràn aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá ní wíwọ̀.

**Ìhá tí àwọn àgbàlagbà lọ́kùnrin àti lóbìnrin kọ sí ìbéèrè ìwádìí**

| S/N | ÌBÉÈRÈ | BẸ́Ẹ̀ NI | IDA ỌGỌ́RÙN | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ | IDA ỌGỌ́RÙN |
|---|---|---|---|---|---|
| 1. | Mo fẹ́ràn láti máa wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá torí pé ó máa n buyìn kún ènìyàn | 29 | 48.3 | 31 | 51.7 |
| 2. | Aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá ní wíwọ̀ máa ń gbé àṣà àti ìṣe Yorùbá lárugẹ | 43 | 71.7 | 17 | 28.3 |
| 3. | Wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá máa ń ṣàfihàn | 20 | 33.3 | 40 | 66.7 |

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| | jíjẹ́ ọmọlúàbí | | | | |
| 4. | ó r ọrùn fún mi láti wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá nítorí pé ó máa ń mú mi rẹwà | 28 | 46.7 | 32 | 53.3 |
| 5 | Aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá wúlò jù aṣọ òyìnbó lọ to rí pé kì í fi ìhòhò ara enì hàn | 45 | 75 | 15 | 25 |
| 6. | Ọ̀pọ̀ àwọn òbí ni kì í ṣè àyẹ̀wò aṣọ tí àwọn ọmọ ń wọ̀ jáde nínú ilé | 39 | 65 | 21 | 35 |
| 7. | Ǹjẹ́ àwọn ènìyàn nifẹ̀ẹ́ sí wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá? | 22 | 45 | 27 | 55 |
| 8. | Ǹjẹ́ àwọn ènìyàn ka aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá kún aṣọ gidi? | 32 | 53.3 | 28 | 46.7 |
| 9. | Ṣé lóòtọ́ ni aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá máa n wíwọ lára tí ènìyàn bá wọ̀ ọ́? | 31 | 51.7 | 29 | 48.3 |
| 10. | Ṣé lóòtọ́ ni pé àwọn ẹni tí kò ríta ló ń wọ aṣọ ibílẹ̀ Yorùbá? | 36 | 60 | 24 | 40 |
| 11. | Owo tí a fi ń ra aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá tí máa n pọ̀ ju àwọn aṣọ ìgbàlódé/òyìnbó lọ | 22 | 36.7 | 38 | 63.3 |
| 12. | Ṣe a lè wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá lọ sí ibi iṣẹ́ ọba/ìjọba bí i ti aṣọ òyìnbó? | 20 | 33.3 | 40 | 66.7 |
| 13. | Ǹjẹ́ a rí ọmọ tí kò nífẹ̀ẹ́ sí wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá nínú ẹbí yín? | 46 | 76.7 | 14 | 23.3 |
| 14. | Torípé aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá nílò fìlà tó bá a mu ni mo fi pa á tí ní wíwọ̀ | 42 | 70 | 18 | 30 |
| 15. | Gẹ́gẹ́ bí òbí tàbí alágbàtọ́, ǹjẹ́ o rọrùn láti dá aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá fún gbogbo ẹbí? | 22 | 36.7 | 38 | 63.3 |
| 16. | Ẹ̀sìn ìgbàlódé kò gbá mí láyè láti wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá | 33 | 55 | 27 | 45 |
| 17. | Àwọn oníṣẹ̀ẹ̀ṣe nìkan ní aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá wà fun | 20 | 33.3 | 40 | 66.7 |
| 18. | Kò sí aṣọ mìíràn yàtọ̀ sí aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá nínú gbogbo aṣọ tí mo ni | 29 | 48.3 | 31 | 51.7 |
| 19. | Mo fẹ́ràn aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá dáradára, ṣùgbọ́n Yorùbá kò já gaara lẹ́nu mi | 31 | 51.7 | 29 | 48.3 |
| 20 | Mo dúpẹ́ pé mo jẹ́ ìran Yorùbá | 39 | 65 | 21 | 35 |

**Àlàyé lórí ìhà tí àwọn àgbàlagbà lọ́kùnrin àti lóbìnrin kọ sí ìbéèrè ìwádìí**

Nínú ìdáhùn si ìbéèrè kìn-ín-ní, ó hàn gbàngbà pé àwọn tó fẹ́ràn láti máa wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá kò tọ́ àwọn tí kò fẹ́ràn wíwọ rẹ̀. Ìdá mọ́kànléláàdọ́ta (48.3%) ní kò fẹ́ràn wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá jẹ́ ìdá méjìdínláàdọ́ta (51.7%) ni àwọn akópa tó fẹ́ràn wíwọ̀ rẹ̀. Ìdáhun ìbéèrè kejì ṣàfihàn pé wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ máa ń gbé àṣà àti ìṣe Yorùbá láruge. Ìdáhùn ìbéèrè kẹta jẹ́ kó yé wa pé wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá kò túmọ̀ sí pé ènìyàn jẹ́ ọmọlúàbí, ìdá mẹ́tàlélọ́gbọ̀n (33.3%) ló ní "bẹ́ẹ̀ ni". Ṣùgbọ́n ìdá mẹ́rìndínláàdọ́rin (66.7%) ló ní "bẹ́ẹ̀ kọ̀". Nínú ìbéèrè kẹrin, àwọn tó sọ pé wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá máa ń mú àwọn rẹwà si jẹ́ méjìdínlọ́gbọ̀n (46.7%), tí àwọn tó mú "bẹ́ẹ̀ kọ́" jẹ́ méjìlélọ́gbọ̀n (53.3%).

Ìdàhuǹ sí ìbéèrè kaàrún jẹ́ kí á mọ̀ pé aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá wúlò ju aṣọ òyìnbó/ìgbàlódé lọ. Ìdá márùndínlọ́gọ́rùn (75%) lò mú "bẹ́ẹ̀ ní", tí ìdá márùndínlọ́gbọ̀n (25%) ta kò ó. Nínú ìdáhùn sí ìbéèrè kẹfà, àwọn ènìyàn tó ní ọ̀pọ̀ àwọn òbí ní kìí ṣe àyẹ̀wò aṣọ tí àwọn ọmọ wọn máa wọ̀ jáde nínú ilé jẹ́ mọ́kàndínlọ́gbọ̀n (65%), tí ìdá márùndínlógójì (35%) mú ìdáhùn "bẹ́ẹ̀ kọ́".

Nínú ìdáhùn sí ìbéèrè kejọ, ìdá márùnléláàdọ́ta (55%) lo ni "bẹ́ẹ̀ ni" ti ìdá márùndínláàdọ́ta (45%) mú "bẹ́ẹ̀ kọ́". Ìdá mẹ́tàléláàdọ́ta (53.3%) ri aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí

aṣọ gidi tí ìdá mẹ́rìndínláàdọ́ta (46.7%) ní "bẹ́ẹ̀ kọ́". Ìdáhùn sí ìbéèrè keje àti ìkẹsàn-án ṣàfihàn ìhà tí àwọn ènìyàn kọ sí wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá. Ìdá márùnléláàdọ́ta (55%) nínú ìbéèrè keje mú "bẹ́ẹ̀ kọ́" tí ìdá mọ́kànléláàdọ́ta (51.7%) ní aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá máa ń wúwọo lára tí ènìyàn bá wọ̀ ọ́ nínú ìbéèrè kẹsàn-án.

Ìbéèrè kẹwàá ṣe àfihàn iye àwọn tí ó sọ pé ẹni tí kò ríta ni ó máa ń wọ asọ ìbílẹ̀ Yorùbá (60%), ti ìdá ogójì (40%) ni ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀.

Nínú ìdáhùn sí ìbéèrè kọkànlá, àwọn akópa tí wọ́n mú "bẹ́ẹ̀ ni" jẹ́ ìdá mẹ́rìndínlógóji (36.7%), tí àwọn tó ní "béè kọ́" jẹ́ ìdá mẹ́tàlélọ́gọ́ta (63.3%). Ìdáhùn sí ìbéèrè kejìlá ni aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá kò ṣe é wọ̀ lọ síbi iṣẹ́ ìjọba tì àwọn ènìyàn ogún (36.7%) faramọ́, ìdá márùndínláàdọ́run (66.3%) ló ní bẹ́ẹ̀ kọ́"

Ìdáhùn sí ìbéèrè kẹtàlá fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọ̀pọ̀ ọmọ ni kò nífẹ̀ẹ́ sí wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá nínú ẹbí wọn tí ìdá wọn jẹ́ mẹ́rìndínlọ́gọ́rùn (76.7%). Ìdá mẹ́tàlélógún (23.3%) ló mú "bẹ́ẹ̀ kọ́". Nínú ìbéèrè kẹrìnlá, ó hàn gbangba nínú ìdáhùn àwọn akópa pé, torí pé asọ ìbílẹ̀ Yorùbá nílò fílà to´ bá a mu ni àwọn kì í fi wọ̀ ọ́. Ìdá àádọ́rin (70%) ló sọ bẹ́ẹ̀, tí ìdá ọgbọ̀n sì ní "bẹ́ẹ̀ kọ́" Ìbéèrè kẹẹ̀dógún ni ọ̀pọ̀ àwọn akópa fèrò wọn hàn pé kò rọrùn láti dá asọ ìbílẹ̀ Yorùbá fún gbogbo ẹbi, ìdá mẹ́tàlélọ́gọ́ta (63.3%) ní àwọn akópa tó sọ bẹ́ẹ̀. Àwọn ìdá mẹ́rìndínlọ́gọ́ta (36.7%) ló ní ó rọrùn láti ṣe bẹ́ẹ̀.

Ìbéèrè kẹrìndínlógún sọ̀rọ̀ lórí ẹ̀sìn ìgbàlódé nibi tí ìdá márùndínlọ́gọ́ta (55%) ti ní ẹ̀sìn ìgbàlódé ṣe àkóbá fún wíwọ asọ ìbílẹ̀ Yorùbá. Ìdá márùndínláàdọ́ta (45%) ní ẹ̀sìn ìgbàlódé kò ní kí àwọn má wọ asọ ìbílẹ̀ Yorùbá. Ìdáhùn sí ìbéèrè kẹtàdínlógún ní àwọn onísẹ̀ẹ̀ṣe nìkan ni asọ ìbílẹ̀ Yorùbá wà fún, ìdá mẹ́rìndínláàdọ́rin (66.7%) ló sọ bẹ́ẹ̀ nígbà tí ìdá mẹ́tàlélọ́gbọn (33.3%) ni "bẹ́ẹ̀ kọ́". Ìdá mọ́kànléláàdọ́ta (51.7%) nínú ìbéèrè kejìdínlógún ní ẹ̀tahóró ni asọ ìbílẹ̀ Yorùbá tó wà nínú asọ òun, tí ìdá méjìdínláàdọ́ta (48.3%) ní asọ ìbílẹ̀ Yorùbá pọ̀ ju asọ òyìnbó lọ. Àwọn akópa tó fẹ́ràn asọ ìbílẹ̀ Yorùbá sùgbọ́n tí èdè Yorùbá kò jọ̀lọ̀ lẹ́nu wọn nínú ìbéèrè kọkàndínlógún kó ìdá mọ́kànléláàdọ́ta (51.7%) tí ìdá méjìdínláàdọ́ta (48.3%) mọ èdè Yorùbá sọ sùgbọ́n tí wọn kò fẹ́ràn asọ ìbílẹ̀ Yorùbá. Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ akópa ló sàfihàn ara wọn gẹ́gẹ́ bí ọmọ Yorùbá, èyí tí wọn jẹ́ ìdá márùndínláàdọ́rin (65%) tí àwọn ìdá márùndínlógójì (35%) bá inú jẹ́ pé àwọn jẹ́ ìran Yorùbá.

**Ìjábọ̀ Isẹ́ Ìwádìí**

Àwọn ìṣòro tí wọ́n dà bí èsù lẹ́yìn ìbejì fún àṣà ìwọṣọ ìran Yorùbá lóde-òní ni a fẹ́ sọ̀rọ̀ lé lórí lábẹ́ ìjábọ̀ iṣẹ́ ìwádìí. Àwọn ìṣòro tó fojú hàn kedere nínú pépà yìí ni pàtàkì nínú àkójọ ìbéèrè tí a ṣe fún àwọn àgbàlagbà àti àwọn ọ̀dọ́ ni, àwọn òbí, ọ̀làjú, ẹ̀kọ́ ìgbàlódé, akẹ́kọ̀ọ́ àti olùkọ́.

**Àwọn òbí:** Ọ̀kan lára ìṣòro àṣà ìwọṣọ ìran Yorùbá ni àwọn òbí jẹ́. Ọ̀pọ̀ òbí ni wọ́n kò fi wíwọ asọ ìbílẹ̀ kọ́ àwọn ọmọ nínú ilé kí wọ́n tó jáde sí àwùjọ. Asọ ìwọ̀kuwọ̀ tí àwọn òbí ń wọ̀ tí àwọn ọmọ ń rí lára wọn ni àwọn ọmọ náà kọ́ lára. Ẹ̀rí máa jẹ́mi ǹ ṣó wa nínú àkójọ ìbéèrè tí a fi síta fún ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nu wò lórí ìhà tí wọ́n kọ sí wíwọ asọ ìbílẹ̀ Yorùbá. Àwọn òbí tí kò nífẹ̀ẹ́ sí wíwọ asọ ìbílẹ̀ Yorùbá pọ̀ ju àwọn òbí tó nífẹ̀ẹ́ si lọ. Èyí wà lára ohun tí ó jẹ́ kí àwọn ọmọ wọ̀nyí kóríìra àṣà wọn, tí wọ́n kò sì lè sọ èdè Yorùbá kó ja gaara lẹ́nu mọ́. Wọn ti gbàgbé pé lára asọ tó se é mú yangàn ni asọ ìran Yorùbá wà lágbàáyé, tí ó sì ń ṣe àfihàn ìwà ọmọlúàbí.

**Ọ̀làjú:** Ọ̀làjú tó gbayé ti mú kí àṣà ìwọṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá máa kásẹ̀ nílẹ̀ díẹ̀ díẹ̀, tí a bá fi wé bí Yorùbá ṣe kàràmàsìkí wíwọ asọ náà sí láyé àtijọ. Onírúurú nǹkan ọ̀làjú bí eré inú sinimá, tẹlifísàn àti nìnù àwọn ẹ̀rọ ìléwọ́ gbogbo ti mú kí àkùdé dé bá àṣà asọ wíwọ̀ láàrin ìran Yorùbá. Oríṣiríṣi àwọn àwòrán asọ tí àwọn èwe ìwòyí ń rí nínú sinimá nínú tẹlifísàn, èrò ìléwọ́ ni wọ́n ń rán tí wọn ń wọ. Àwọn asọ tí kò bo ìhòhò ara ni wọ́n ń wọ̀ báyìí. Àwọn ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ni wọ́n ń lò láti fi àtẹ̀jíṣẹ́ ránsẹ́ sí ara wọn. Àtẹ̀jíṣẹ́ orí afẹ́fẹ́ wọ̀ọ̀sọ́ọ̀pù àti ìṣàmúlò i-meèlì máa ń fún wọn ni àǹfààní.

**Ẹ̀kọ́ Ìgbàlódé:** Ẹ̀kọ́ ìgbàlódé tí àwọn ọmọ ń gbà ní àwọn ilé iwé káàkiri orílẹ̀ èdè náà jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ìṣòro tó ń dojú kọ wíwọ̀ aṣọ ìran Yorùbá. Púpọ̀ àwọn ìmọ̀ ẹ̀kọ́ wọ̀nyi ní kò fàyè gba wíwọ aṣọ ìbílẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, ọmọ tí ó bá ń kẹ́kọ̀ọ́ nípa ìmọ̀ òfin (Law) ni iru aṣọ tí ó gbọ́dọ̀ máa wọ̀ lọ fun ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ni gbogbo ìgbà. Bẹ́ẹ̀ ní àwọn ọmọ tì ó ń kọ́ nípa ìmọ̀ ìṣègun

(Medicine) ìmọ̀ ìpòògùn (Pharmacy) ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ìṣirò owó (Accounting) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn aṣọ ìbílẹ̀ kò ráyè fẹsẹ̀ walẹ́ nínú àwọn ìmọ́ ẹ̀kọ́ ìgbàlódé wọ̀nyi.

**Olùkọ́:** Ìṣoro yìí kìí ṣe kékere nínú àwọn ìṣoro tó ń kojú àṣà wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá. Àwọn olùkọ́ èdè àti lítíréṣọ̀ Yorùbá tí ó yẹ́ kí wọ́n jẹ́ àwòkọ́ṣe rere nínú gbigbe àṣà ìwọṣọ̀ ìbílẹ̀ Yorùbá láruge ni ọ̀lájú ti gbé wọ̀ bi ẹ̀wù. Àwọn aṣọkáṣọ ni ọ̀pọ̀ àwọn olùkọ èdè àti lítíréṣọ̀ Yorùbá ń wọ̀. Àwọn aṣọ bii shirt àti trouser, crazy gens, crazy skirt, banging top, craz top, born-short, off shoulder, skirt àti blouse àti àwọn aṣọ èṣù bèlèké mìíràn. Àwọn olúkọ́ tó yẹ kí wọ́n jẹ́ agbáṣágá ni wọ́n ń bomi pa iná àṣà lóde-òni. Ṣé olúkọ tí kò wọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá ni yóò sọ fun àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pé kí wọ́n máa wọ aṣọ ìran Yorùbá wá sí ilé ìwé? Kò sí ọ̀rọ̀ lẹ́nu ọmọ ìyá olè. Owó yẹpẹrẹ tí àwọn olùkọ́ èdè àti lítíréṣọ̀ Yorùbá fi mú wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ ǹ ṣe àkóbá fún ìfẹ́ tí ó yẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní sí wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá.

**Akẹ́kọ̀ọ́:** A kò lè yọ ọwọ́ kílàńkó àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kúrò nínú ìṣòro tó ń dojú kọ àṣà aṣọ wíwọ ní àwùjọ Yorùbá. Bí ó ti wù kí olùkọ́ fẹ́ràn wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá tó, tí ó sì n sọ pàtàkì wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́, tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kò bá fi ìfẹ́ hàn sí wíwọ aṣọ yìí, kí wọ́n sì mú u níbààdà, òfo ọjọ́ kejì ọjà ni ìgbìnyànjú olúkọ́ yóò já si.

## Ọ̀nà Àbáyọ

Níwọ̀ǹgbà tí a ti mọ àwọn ìṣoro tó jẹ́ èṣù lẹ́yin ìbèjì fún àṣà yìí, àwọn ọ̀nà àbáyọ sí àwọn ìṣòro tí a là sílẹ̀ ṣẹ́ pẹ́rẹ́. Àkọ́kọ, àwọn òbí gbọdọ̀ fi ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí kọ́ àwọn ọmọ látilé ki wọn tó jáde síta. Wíwọ aṣọ tó bo ìhòhò ara jẹ́ ọ̀kan lára ìrísí ìwà ọmọlúàbi. Kí àwọn òbí náà yàgò fún aṣọ ìwọ̀kuwọ̀ tí àwọn ọmọ lè máa wò kọ́ṣe látara wọn, ki wọ́n máa sọ́ èdè Yorùbá si wọn nínú ile. Tori Yorùbá bọ̀ wọ́n ni, ile la tí n kẹ́ṣọ̀ọ́ ròde.

Kí àwọn ìlé iṣẹ sinimá, tẹlifíṣàn àti rédíò máa gbìnyànjú gbé àwọn ètò tí yóò ṣe ìgbéláruge fún wíwọ àwọn aṣọ ìbílẹ̀ yàtọ̀ sí gbigbé àwọn aṣọ ilẹ̀ òkèèrè láruge ju tí àwọn aṣọ tiwa-n-tiwa lọ. Kí àwọn alákòóso àti àwọn olóòtú ètò tí yóò máa jáde sínú afẹ́fẹ́ máa ṣe àyẹ̀wò wọn dáradara kí wọ́n tó máa gbe sínú afẹ́fẹ́. Èyí ló lè mú kí àwọn atọ́kùn ètò gbogbo ní ìjánu lórí ètò tí wọ́n yóò máa ṣe.

Lóòtọ̀ ni a mọ̀ pé àwọn ìmọ̀ ẹ̀kọ́ ìgbàlódé kan ní àwọn aṣọ tí a mọ̀ mọ̀ wọ́n kí irú àwọn aṣọ bẹ́ẹ̀ jẹ́ èyí tí kò ní máa fi ìhòhò ara wọn hàn bí àwọn aṣọ tí wọ́n ǹ wọ̀ báyìí.

## Àgbálọgbábọ̀

Ohun tí a gbìyànjú láti wò nínú iṣẹ́ yìí ni ohun tí ó ń mú ẹ̀bọ́ èyìn bá àṣà aṣọ wíwọ̀ láàrin ẹ̀yà Yorùbá láyé òdé-òní. A tẹ̀síwájú láti wo oríṣiriṣí àwọn aṣọ tí ìran Yorùbá ń wọ̀ láyé àtijọ́ tí kò fi bẹ́ẹ̀ sì mọ́ láàrin ìran Yorùbá, yàtọ̀ sí àwọn aṣọ èṣù bèlèké. A dábàá lóríṣiriṣi èyí tí ó lè ta wá jí sí mímú àṣà yìí lọ́kùnkún dùn. A nígbàgbọ́ pé tí awọn àbá wọ̀nyí bá di mímúṣẹ, àyípadà a tun yóò dé bá ìhá tí àwọn ọmọbibi Yorùbá kọ sí àṣà wíwọ aṣọ ìbílẹ̀ ìran Yorùbá.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Adéoyè, A.A. (2003). Ìtọpinpin orírun àṣà pẹ̀lú àgbéyẹ̀wò àwọn ohun Ìṣẹ̀ǹbáyé Ọ̀yọ́. Immacullate publishers

Adéoyè, C.L. (1979). Àṣà àti Ìṣe Yorùbá. London Oxford Press

Adérìnóyè, R. (2019 ay). Dandan lẹ̀kọ́. Ibadan. Rasmed Publications Limited.

Olúwajọbi, O. Àti Ọláwoyè, S.A. (2016) Ẹ̀kúnrẹrẹ́ Ẹ̀kọ́ Èdè Yorùbá fún Alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀. Ìwé kẹrin (Àtunṣe). Ibadan. Pamat Educational Publishers.

Tìámíyù, R.O. (2004). Àṣà, Ìṣe àti Òrìṣà ilẹ́ Yorùbá. Ibadan. Akacomm Publications Limited

Wiliam, O. F. (2018 ay). Táíwò àti Kéhìndé. Ìwé keta (Àpilèsa ètun fún UBE). Ibadan.